IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 608 TUESDAY MAY 19, 1964 (2D)

## Obinrin Kan Ju Ọmọ Rẹ Sinu Ile IYagbẹ !

ỌBALENDẸ:— Ariwo ta ge e, pe, ẹgba mi o gbogbo ẹnyin ara ile, nigbati ọkunrin onişẹ alẹ kan, Amusa Adebisi fẹ gbe garawa ile - iyagbẹ kan ni opopo Adeniyi Obalende ni alẹ ọjọ ẹti ti işe ọjọ kẹrinla oşu yi ti o s i b a ọmọ tuntun kan ti obinrin kan jin s nu garawa iyagbẹ na ninu igbẹ rirun ile na.

Ariwo ọkunrin yi ti o ke lo ji ọpọlọ pọ awọn enia inu ile ati awọn aladugbo ti nwọn ti sun ni ọjọ na pe "Ẹ tun lọ pe Ọlọpa fun mi."

Lẹsẹkẹsẹ ni ọgbẹni Adebisi sare lọ si Bareke awọn ọlọpa ti o si lọ pe awọn ọlọpa wa pe ki nwọn o wa wo engmọ ti on ri loni, eyiti on ko ti ri lati ọjọ ti on ti nşe işẹ on ni Eko.

Nigbati awọn ọlọpa na de ni o b a mu wọn wọ inu ile iyagbẹ na lọ, nwọn si ba ọmọ tuntun na ninu ile iyagbẹ garawa.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa pe gbogbo awọn ara ile na jọ, nwọn si ji awọn ti o ti sun lati jẹki gbogbo wọn o le fi oju wọn ri işẹ ti ọkan ninu wọn şe.

Awọn Ọlọpa ko ti mọ ẹniti o ni ọmọ na, şugbọn ọmọ na ti ku. nwọn si nşe iwadi ọrọ na lọ ọ, bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ o ma a gbọ ninu iwe Irohin wa.

# IJỌBA IPINLẸ ILA ORUN PE APAPỌ IJỌBA L'ẸJỌ!!

EKO:- A gbọ sọgbanu ni agba iyanu irohin ti o kan gbogbo enia kan ni ọsan ana jẹ fun gbogbo awọn enia ilẹ Naijiria nigbati Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria pe Apapọ Ijọba Naijiria lẹjọ sinu ile ẹjọ ti o ga julọ fun orilẹ ede Naijiria fun ẹsun magomago lori abayọri eto ikania.

Ninu ẹjọ ti Ijọba na pe ni ọsan ana Minista Alamojuto eto ẹjọ ati ofin fun Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria. ọgbẹni D. O. Ibekuwe şe alaye ninu iwe ipẹjọ na pe' Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba ko şe eto na lọna ti o dara to.

Iwe ipẹjọ na tun şe alaye siwaju pe, Ọgọọrọ aşişe ti kọ şe fi oju foda, ti oju ti ri ti ẹnu kọ gbọdọ ma sọ lo wa ninu aşişe eto ikania na.

Siwaju si, iwe ẹjọ na sọ pe, ko si ẹniti o fun Apapọ Igbimọ eto ikania na laşẹ ki nwọn to gbe abayọri eto ikaina na jade.

O tun sọ siwaju pe nwọn kọ fun Igbimọ na ni aşẹ lati şe işẹ wọn yekeyeke lọna ti o tọ ati ọna ti o yẹ, eyi lo si mu oke şoro ati idiwọ wa fun awọn enia na, ti o si tun fa ifasẹhin wa fun wọn.

Ni ipari, ipẹjọ na şe ala ye pe, Apapọ Ijọba Naijiria ko ni aşe kan labẹ Ọrun yi lati gba abayọri eto ikania na nitori aşişe ati aidọgba mọ ara wọn ti o wa ninu eto ikania na.

Onirohin wa kan ran wa

WO OJU EWE KẸFA



Dọkita M I Okpara
ALAKOSO IJỌBA IPINLẸ ILA-ORUN

## Adegbenro Ja Okun Irọ

IBADAN:- Alhaji D. S. Adegbenro, Aşiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre ninu Ile Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ti sọ fun awọn oniwe irohin ni irọlẹ ana ni Oke-Ado Ibadan pe ọrọ ti o jade ninu awọn Iwe Irohin lana pe, ẹgbẹ Afẹnifẹre fẹ dapọ mọ ẹgbẹ Dẹmọ.



Alhaji D. S. Adegbenro
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ile Asofin Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria

Alhaji Adegbenro tun şe alaye fun ipade awọn oniwe irohin pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ko tun gbọdọ ba awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ şe pọ mọ lailai bi awọn ọmọ ẹgbẹ na basi fẹ pada si ẹgbẹ Afẹnifẹre ko si ohun kan labẹ ọrun ti nwọn le şe ti awọn fi le gba wọn pada.

Alhaji na tun şe alaye pe, ọrọ na jẹ iyalẹnu lati gbọrọ ti nwọn sọ pe Oloye Akinfọsilẹ Minista Alamojuto eto işẹ Waya fun Apapọ Ijọba Naijiria sọ ni Ilesha ni opin ọsẹ ti o kọja yi.

Irohin na sọ pe, awọn ọmọ ẹ g b ẹ Dẹmọ lọ ba Alhaji Adegbenro nwọn si mbẹ wipe ki Alhaji na jẹki awọn da gbogbo rẹ pọ mọ ara wọn nitoripe ọkanna ni gbogbo wa.

Şugbọn Alhaji Adegbenro sọ ni Ibadan ni irọlẹ ana pe ọrọ ti o jade ninu awọn iwe irohin ki işe otitọ o si jina si ododo, eyiti ole şi ara ilu lọna kuro lọju ọna.

Nigbati oniwe irohin wa Ejongboro bere ọrọ lọwọ Alhaji Adegbenro pe, "Njẹ ti awọn ti o ti salọ ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ba p a d a wale wa bẹbẹ nkọ, n j ẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre yio g b a wọn pada?"

Alhaji Adegbenro da oni Iwe i r o h i n wa Ejongboro l o h u n p e, "ohun ti nwọn ri ti nwọn fi şakuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre, ko ti kuro ninu ẹgbẹ na, awa ti a wa nibẹ tẹlẹ na ni a si tun wa ninu ẹgbẹ na, ti Ọlọrun ba si w a loke ọrun, ko si ohun ti o le şi wa nipo pada

Ni ipari ọrọ rẹ, Alhaji Adegbenro wa pari ọrọ pe, "Mo fẹ ki gbogbo aiye mọ dajudaju pe, nko mọ ohunkohun ninu irohin ti o jade ninu awọn iwe irohin na.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 6)

Nibiti mo ba itan mi de lana niyi. Ẹ ma a ka lọ.
Ogboju-le-Ogun o ṣe o ma ṣe o, ọran ti ẹda yi ko kere, ko jẹwon, ko si jowo a fi iku. Ẹniti o ba rin ninu Igbo Ọba pipa ni abọsibọsi ẹni to pa "Egbin" Ọba to tun kẹja Ọba, Iku ya atọkọ ni ipa.

Iku ni si ya ọrẹ meji lapapa-adedo. Iku ni fọle adun, on ni si ṣe Atẹgun agbara, Mo fẹran rẹ pupọ o wu mi lọkuanu. Ọna wo ni ao gbe gba ti ago bubu ru yi yio fi re ọ kọja?

Ogboju - le- Ogun mikanle hihin ati awọn ẹgbọn rẹ, igbayi gan ni nwon to mọ pe awon daran. Ogboju le-ogun pe „O ṣeun! ṣeun! o ṣe pọ o pọ. Ẹniti o ba ṣe ni lori, ka dupẹ ka le na lọgọ ẹnu, ka sọ pe o ṣe pọ!

Niwọn igbati Ọlọrun ba mbẹ ikọ ki i k'ejo lẹsẹ, gedegede la o yọ Ohun kan lo ju ti mo fẹ mọ „Njẹ iwọ ba le fẹ mi bi? Wi fun mi ki ngbọ ọmọ ọba gba pe on yio fẹ ẹ o wa ku ati sọ n'le fun ọba ati iya rẹ,, to-

nu igbo lati lọ wa awọn ọdaran na ri. Nwọn koi ti wa wọn jinna ti ọwọ f i tẹ gbogbo wọn, wọn de wọn ni ṣẹkẹ-ṣẹkẹ, nwọn lu wọn tobẹ gẹ ẹ, t i oti jẹ pe ẹmi kan lo ku lẹnu wọn ki nwọn to de iwaju ọba na.

Nigbati ọba Coju k a u wọn, ko tilẹ fẹ gbọ ọ r ọ kankan lẹnu wọn ki o to fẹ bẹ gbogbọ w ọ n lori ọpẹlọpẹ ọmọ rẹ obinrin ti o wa lọdọ rẹ. On ganan ni ẹniti o fun un ni suru pe ki o to le pa enia o ni lati gbọ ti ẹnu rẹ.

Ọba gba ti ọmọ rẹ ko si pa wọn ṣugbọn o paṣẹ pe ki awọn ọlọpa mu lọ si tubu. Ni oganjọ oru, ọmọ'ba dibọn, oke lati ojo orun

ojẹ eyi alakisa, ọde lusan ni o fẹ fẹ o si wi fun ọmọ rẹ wipe on yio ma ro re. o si lọ si ọdọ baba rifa ilu, osi fere lowo rẹ bi ọmọ on ba ma fẹ Ogbojule-ogun

Ati wipe bi oba jẹ on n o m ṣe fire ọrọ yi soro pupọ nitori ko gbọdọ purọ fun ọba ilu, o si sọ fun wipe ọmọ na yio ṣe ọmọ rẹ ni anfani ko si ni si ija larin wọn.

Ọkan Ọba rẹwẹsi, nigbati o gbọ ohun ti adifa sọ fun, o paṣẹ pe ki a da wọn silẹ, ki nwọn si di ominira Ṣugbọn ohun meji lo mba Ọba ninu jẹ, ekini ko fẹ ki ọmọ on fẹ Ogboju-le-ogun sọmọ Ajẹni ko toripe gbo iṣesi rẹ ko jọ ti Sanmarilu.

Gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ, ẹniti o nrin irin ajo ko le mura bi ẹniti o nlọ si ode iyawo, awọn ni Ogboju le ogun san mọ idi kijipa lo wọ lewu o si ti fọ o to ọdun kan, toripe lati igbati o ti bẹrẹ irin ajo rẹ idamu ti on ati awọn ẹgbọn rẹ mba pade ko mọ niwọn

Ijọ ki nwọn ti nwọn mọ ie ijọ ki nwọn sapamọ si inu igbo fun bi ọjọ mẹta, eyi ko jẹki nwọn ranti ati tọju ara wọn.

Onjẹ ni nwọn ndu. Ekeji ẹwẹ, ti inu Ọba tun fi bajẹ ni pe Ogun ti adifa sọ pe yio wa ko ilu wọn ati pe Ogboju le ogun ni yio gba wọn silẹ Oba bẹrẹsi ro ọrọ

LATI OWỌ
**J. O. Shoyinka**

yi, ọkan rẹ ko balẹ toripe o mọ daju pe Ifa ki I purọ atipe ti on ko ba fi ọmọ on fun Oboju le ogun ko si ani-ani ogun yio ko wọn ni igbekun.

Atijẹ, atisun di ẹ fun Ọba o nro ọrọ yi lojojumọ o gbẹ sooro, o ku ekida ori bi ẹja efolẹ. Gẹgẹbi ẹnyin paapa ti mọ, ti inamu ba ba Ọba, o ba gbogbo awọn ẹbi rẹ ati ilu, nitoripe ko ni raye gbọ tiwọn.

Ti Ọba yi ba nrin lọ tabi ti o ba joko a ma a nikan da sọrọ biwere.



Aworan Oke yi ni ti Ajiran Ilu Awọn Oku

ri pe ọba ko gbọdọ mọ pe ẹda alaye kan wa ninu Igbo on.

Ni aṣalẹ ọjọ kan, Ọba gun ẹṣin rẹ o naju lọ si inu igbo rẹ gẹgẹ bi aṣa ọba yi. Ohun kini tio ma kọkọ ṣe nipe ti o ba de inu igbo, yio kọkọ su'e pe „Egbin

O sufe titi' kegbin ara fun pe nwọn ti pa a, bẹ sihin obẹ sọLun, ko ri, ra. Bi oti npada bọ si ji pẹlu ibanujẹ ni ori awọn ọmọ onilogbo lẹba ọ n a nWọn ta a paku "Egbin" y i ti ina, nwọn y a n a n funọ jijẹ, ko tilẹ s i ohun t i obi ọ b a ninu b i ẹ j a wura rẹti nwọn nsunjẹ.

O yara gẹṣin pada lọ si ile bi monamona, lati lọ pe awọn Ọlọpa rẹ ti bẹ si-

bi enipe on nla ala, ọba ati Ayaba sare dide lati le mọ ohun ti o ṣẹlẹ si ọmọ wọn.

Nigbati nwọn d e i n u iyara ti o wa, nwọn ba o nlagun bẹrẹ-bẹrẹ b i ẹniti orun ago kan ọsan pa, o jo ko lori busun rẹ-Baba rẹ si bere lọwọ rẹ pe kini ṣe ti o fi ki gbe lati oju orun wa.

Ko s i d a wọn lohun, nigbati ko dahun ni Baba rẹ wa ronu lọ titi, omi si fẹ bọ loju rẹ, ni ọmọ rẹ yi ṣẹṣẹ sọ fun un wipe, ọkan ninu awọn ọdaran yi ni ni mo fẹ fẹ eyi ti a npe ni Ogboju lo-gun.

Nigbati baba rẹ gbọ eyi inu rẹ bajẹ osi sọ fun wipe



# Okpara Ati Sardauna Kọlura Lori Ọrọ Enia Kika

Olotu Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakubo Dokita M. I. Okpara kọlura pẹlu Olotu Ipinlẹ Ariwa ati Olori ẹgbẹ N P C Alhaji Ahm du Bello Sadauna ilu Sokoto lori ọrọ enia kika ti ọdun 1963 nigbati nwọn nṣe ipade lori awọn Olotu Ipinlẹ ilẹ Naijiria pẹlu Olotu Ijọba Apapọ Ọlọla Abubakar ni Eko lọnulọlọyi.

Onirohin wa fi ye wa pe gẹgẹbi aṣe gbọ nwọn pari ọrọ enia kika to le mu ariyanjiyan wa larin awọn Olotu na ṣugbọn nibẹ ni gbogbo ọrọ na si tun ti buru ju bẹ lọ.

Onirohin wa fi ye wa pe gẹgẹbi ọrọ ti nwọn ri gbọ nipa ọrọ enia kika ti nwọn si nsọ pe nwọn ti pari ọrọ na pe ko si si ipari kankan lori ọrọ enia kika rara.

Gẹgẹbi ọrọ ti arigbọ pe nse ni Dokita Okpara si fi ake Lọri nigbati awọn Olotu yio fi nsọrọ leri ọrọ enia kika. A si tun gbọ pe nṣe ni Olotu Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ O r u n. Oloye Dennis Osadebey si fi ara mọ Olotu Ipinlẹ Ila Orun.

Oloye Osadebay ko si fi ara m ọ eto enia kika ati pe ko si ni gba lati fara mọ iru eto na rara.

Ṣugbọn Sardanna ati ẹlẹgbẹ rẹ lati Ipinlẹ Iwọ Orun si duro ṣinṣin lati fara mọ eto enia kika na ti o si fi han pe enia to wa n i ilẹ Naijiria si jẹ (55 milliou)

Irohin tun fi ye wa pe Dokita Okpara pẹlu Sardanna si kọlu ara wọn nibi k a n nigbati nwọn nsọrọ lori ọrọ eto enia kika na

Ọrọ na si buruju bi ati nsọ yi lọ to si jẹ wipe Olotu apapọ t o si j ẹ alaga ipade na le si la Olotu Ariwa pẹlu Olotu Ipinlẹ Ila Orun ki ọrọ na ba ga ju bẹ lọ.

Eto nipa ọrọ enia kika na ko si ni oju si ti i kan rara ati pe awọn to fi ara mọ ninu awọn Olotu na si jẹ meji awọn ti ko fi ara mọ si jẹ meji. Eleyi a si mu ki Olotu ti o jẹ onilaja si ọrọ eto enia na lati ṣe gẹgẹbi ọrọ na yio ṣe yanju sibi kan.

Onirohin tun fi ye wa pe awọn ti yio faramọ Sadauna yio pọ ju nitori igbakeji rẹ ninu ẹgbẹ N P C Ọlọla Alhaji Abubakar yio faramọ pẹlu. A si tun ri gbọ pe ki ki Ọlọla Abubakar to le la ija na ni pe nṣe ni o si sọ pe on faramọ eto enia kika na eyi to fun Ipinlẹ Ariwa ni enia to pọ ju lọ.

Eleyi fi han wa pe Sardanna ati Akintọla si wa ni Ipinlẹ kan na, ọpọlọpọ ni...n awọn enia to wa si ipade na lọ si nṣe ipade orisirisi nipa eto ọrọ enia kika na

Irohin tun fi ye wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ N C N C si nṣe ipade lori ọrọ na lati l e mọ e y i ti nwọn yio ṣe lori ọrọ na

## ✶ YẸ IRAWỌ RẸ WO ✶

AQUARIUS (Jan 21 – Feb 19) Ohun abami kan yio ṣẹlẹ larin ile rẹ loni ti yio mu igbadun ati ayọ dani.

PISCES (Feb 20 Mar 20) Ire ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun ọ iwọ o si ri nkan iyanu kan pẹlu.

ARIES (Mar 21 – April 20) Iṣẹ rẹ ati gbogbo nkan rẹ yio ma gun regerege, ire ati arisiki yio si ṣiji bo ọ.

TAURUS (April 21 – May 21) Bi o na nko isọwọ awọn ẹlẹgbẹ rẹ lọ si o..e, arisiki yio ma ba ọ gbe.

GEMINI (May 22 – June 21) Ọrọ pataki kan to ti wa nilẹ yio pari si rere, ki o si dupẹ lọwọ awọn alagbara ẹlẹgbẹ ti o ni.

CANCER (June 22 – July 23) Iwọ yio ri owo logba loni bi o ba si uta orire, iwọ yio jẹ owo jaburata.

LEO (July 24 – Aug 22) Ibiti o ngbero lati lọ, kẹi ti si dajudaju rẹ pe yio ṣeṣe lakoko yi.

VIRGO (Aug 23 – Sept 23) Ọ..an ninu iṣẹ ti o nṣe yio fa ire nla kan jade ti yio ṣe ọ ni anfani.

LIBRA (Sept 24 – Oct 23) Bi o ba nfẹ alafia ati ifọkanbalẹ arin iwọ pẹlu awọn ẹbi rẹ, nṣe ni ki o ba wọn fẹ nkan ti nwọn fẹ.

SCORPIO Oct. 24 -Nov 23:- Kiyesi gẹgẹbi o ti ṣe nnawo rẹ bibẹ kọ iwọ yio jogun ofifo.

SAGITTARIUS(Nov.-23 Dec. 22:- Akoko yi le fun ọ, igb... okaka le wọle okokoro.

CAPRICORN (Dec. 23-Jan. 20) Ayipada si rere fẹrẹde ilọsiwaju yio si de ṣugbọn ko ni ya kiakia.

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kerinlelogun oṣu karun (24/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Akọwe Agb.


## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun To Nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWA RẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INA KUNA. KI O LE LO ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
"Oluwa ọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin.

WAS SALM"

AKIYESI: Gbogbo Musulumi Ododo lo ye ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA.
Iye Owo 5/6 £3 fun dọsini
MANAGER
N2/99 SHITTI STREET,
Ibadan



## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin lobe ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi - oju Ilaogun ati ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara papọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orișirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI ..Ọ TI WỌN NPE NI:-

### Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orișirisi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi lwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orișirisi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IWE SI OLOTU

## Mo Kin Ọgbẹni Shoyinka Lẹhin

Olotu Iọu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye lati kin Ọgbẹni J. O. Shoyinka lẹhin ọrọ rẹ ti o sọ ninu iwe Irohin nyin ti ọjọ karun oṣu karun Ọdun yi nipa pe ki awọn osewe Yoruba da ẹgbẹ kan silẹ gẹgẹbi ẹgbẹ kan pataki ti yio wa lati ma ṣe iranlọwọ fun gbogbo ẹniti oba ni ọgbọn lati ma ṣe iwe l'ede Yoruba Ṣugbọn ti ko si agbara owo lati fi ṣe iwe na.

Emi na gba ọrọ rẹ yi, mo si wa nbẹ gbogbo ẹnyin Ọjọgbọn Yoruba lati kin mi lẹhin ọrọ yi ki ẹ si gbimọ lati tete da ẹgbẹ na silẹ nitori bi ẹ ba da ẹgbẹ na silẹ yio tun fun ede wa ni ilọsiwaju ola ati paapa eyi yio tun bọ mu awọn Ọmọ wa mọ nipa ijinlẹ Yoruba.

Ẹnyin alagba wa, Ọmọọba Adefarakan (Erukubodo) Ọgbẹni Ọlabintan Oladipọ Yemitan, Rev. E. A. Atilade, Tunji Adeọsun, E. O. Olofin, Alagba Olurebi Williams, J. O. Odunjọ ati bẹbẹ lọ, ẹ lọwọ ẹ ba wa se eto ati da ẹgbẹ na silẹ fun anfani awọn ti o mbọ.

Ao ma reti rẹ o.

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ fun mi o, Iwaju ni ọpa ẹbiti nyin yio ma resi o

Emi ni
Ọmọ-Ọba L. A. Babalọla
ỌYỌ.

## Esi Alapara Ibadan Lara

Olotu, pẹlu itẹriba ni mo fi tọrọ aye ninu iwe Irohin Imọlẹ rẹ lati ṣe ọpẹ fun Alapara Ibadan, nipa esi ti o kun fun ẹgbọn ati lakaye ti o fun ẹgbẹni Yesufu Oyinloye sinu iwe nyin ti ọjọ Ri ti iṣẹ jọ kẹtala oṣu karun ọdun yi, nipa ẹre Ẹyọ Ajamouṣa HUHAHA ti mo ti ko sinu iwe nyin ni ọjọ kejidinlogun oṣu kẹrin ọdu yi.

Mba ti fun Ọgbẹni Yesufu Oyinloye lesi bi ki i ba ṣepe, awọn iṣẹ ribiribi ii o mu ikanju dari to wa fun mi lati yanju. Mo dupẹ gi digidi fun Ọlọrun ti O ṣe inawo fun mi yanju awọn awọn iṣẹ na Alapara Ibadan, mo dupe lọwọ rẹ lẹẹban si. O ti fi esi ti o gbadun ju eyiti mo ti ni era la ti fi.

Oluwa ki O ma a fi kun lakaye Alapara, ki O si fun un ni ẹmi gigun ti yio ni oore ninu,

O di ọwọ nyin ọgbẹni Oyinloye ni,

Hadji Y. A. Disu,
EKO

## Ẹyọ Kiṣe Oriṣa

Inu mi yio dun pupọ bi olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laiye diẹ ninu iwe rẹ oloyin mọ lati da ọgbẹni Yesufu Oyinloye loh un ọrọ ti o sọ ti o jade ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ kejidinlogun oṣu kẹrin ninu ọdun yi.

Ọgbẹni Oyinloye sọ wipe nigba ti awọn nfẹ ki Ọlọrun ba wa pa-ina Keferi sibẹsibẹ Alhaji Y. A Disu tun ngbin kun ni nipa ti ere Ẹyọ ti Ọlọla Coker fẹ ṣe fun irantii baba rẹ.

A ma ya enia lẹnu ti ẹniti oye ko gbọn ti ko gbọn, ẹniti oye ki o mọ oye ti kosi mọ oye pẹlu, Ki enia bọ oriṣa oyatọ siki enia ṣe Ẹyọ.

Mo fe ki ogbẹni Oyinlọla sọ iyatọ ti o wa larin Ẹbọ ati Sara nitoripe ede Larubawa ni sara itumọ rẹ ni ede Yoruba ni ẹbọ, koyẹ ki ama fi ede tan ara wa jẹ.

Ko yẹ pe nigbati aba ti di Imọle ki a si gbagbe nkan iṣẹdalẹ wa, Awọn Alhaji sọ fun wa pe, keferi wa ni Mẹkka ṣe awọn Alhaji ile wa lo tun lo lọ si ọdun?

Ẹba enia rere jẹmọ Alhaji Disu Awẹlẹwa ọkunrin, alawada sioi pẹlu,

Emi ni
J. Ọla Wins,
Itirẹ-Mushin

## Alla Nfẹ Omi

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu Irohin Imọlẹ ba le ba mi tẹ ọrọ mi jade ninu iwe rẹ ti njade lojojumọ fun araiye paapa Ijọba Ipinlẹ Ariwa ki ole tete fun wa ni ẹrọ omi ti ao mọ mu ni asiko ti ẹrun ba de

Wahala nla ni amọ ṣe ki a to ri omi pọn irin to iṣe lọtọ a nrin to ibusọ mẹrin ki ato ri omi pọn omi na ko si dara to rara kiki ẹrọfọ ni omi ti anmu tulasi ni anfi nmu omi ti ko dara aisan ko ni pẹ se Oluwarẹ emiran si le fa iku pẹlu nitoripe omi ti ko dara na a tokun oriṣiriṣi awọn arun,

A nbẹ ijọba ki wọn ranwa lọwọ gẹgẹbi eto ilọsiwaju ọlọdun marun yi ki o to pari anfẹ ki ẹran wa lọwọ lati fun wa ni Ẹrọ omi ti ao mọ ponmuti ao tun mọ fi wẹ ati foso pẹlu.

Ọpọlopo ni ki ri omi fẹ nwọn ki ri omi lati fi fo aso won ẹniti ko ri omi mu ni yio wa ri omi foso Iya nla lo njẹ wa ẹ ba wa gbon nu ki ela bo ninu wahala airi omi mu

Ẹku iṣẹ Olotu iwaju ni ọpa ẹbitl yin yio mọ rẹsi amin

Emi ni
R. A. Abikoye
ALLA

## Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI - Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHELET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia ju da si fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu ẸJẸ ARA' bi Mọnamọna,




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si ni kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyọn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a rangọ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, oriṣiriṣi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ ba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo Iwọ yio si ma a rohin rẹ fuu ẹlomina pẹlu

Bere Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.



BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA

Dan wa wo lẹẹmẹjọ ki o ri iyatọ

# Ala ati Itumọ Rẹ

Ahere-: ti enia ba wa ninu rẹ, ala rere ni, ti o ba dahoro ṣẹra nipa iku airo tẹlẹ

Awọ : ti oba fọ lọwọ rẹ, ami buburu ni eyi

Abiku-: bi oba ri abiku loju ala, ami ti ko dara ni eyi

Ala-: bi o ba nla ala loju ala iwọ yio gbọ iro rere kan lati okere ti yio ṣe ọ ni anfani

Adaba-: Ala rere ni eyi, iwo yio gbọ iro rere ti yio ṣe ọ ni rere

Apata-: ti oba ri apata loju ala, ala iṣẹgun lori awọn ọta rẹ ni eyi

Alapa-: Ti o ba ri alapa ogiri loju ala, ṣọra gidigidi ki o si kun fun adura riteri aiṣan ojiji ti o le gba emi rẹ lojiji
Ọka-: ti o ba ri ọka baba l'oju ala' ma yọ, owo nbọ niyẹn

Bata-: ti oba ri bata yala nwọn nta ni tabi wọọ ṣọra

Baluwẹ-: ti o ba nwẹ ni baluwẹ tabi ori ẹniti o nwẹ nilẹ aiṣan ni

Balogun-: ti o ba ri balogun tabi ọgagun Iwọ yio ri asiki akọtun laipẹ ọjọ

Akiyesi; Mara iwe iroyin Imọlẹ nigbagbogbo fun itumọ ala rẹ. Iwọ papa le bere itumọ ala rẹ lọwọ

Josefu Alala
c/o Poster Agent
Itirẹ via Yaba.





The NEW de luxe
HOOVER cleaner
*Buy yours NOW at:*
**LEVENTIS TECHNICAL**
New showrooms at Iddo, Marina & Mainland Stores, Kingsway, P.Z., U.T.C. Stores and also throughout our branches in Nigeria.


# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi taaboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbẹgbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itire bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josefu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Şişe | |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Isẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/ |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinkan
c/o Postal Agen
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.

or 1,Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ

